**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose kerindinlogbon: Osu kefa Ojo karundinlogbon, 2017**

**Akori oro: Ore-ofe Oluwa** –Apa kini

**Eko kika: Efesu 2: 1-8**

## **Afihan**

Ore-ofe je ebun-ofe ati ojurere ti enia ko ye fun lati odo Olorun si eda-enia, eyiti o farahan ninu igbala awon elese; pelu fifun nwon ni ebun-orun ati ibukun. A tu le se salaye ore-ofe gegebi iranlowo nipa ti Emi, ti enia ko ye fun: ti Oluwa fifun eda-enia fun iyasimimo ati isodotun. Ore-ofe je ife Olorun tabi Emi-Olorun ti o nsise ninu awa enia fun iwenumo ati okun lati le so eda-enia di otun nipa ti ara ati ti Emi.

Eda-enia ni lati mo wipe, ore-ofe Olorun ni ko jeki aiye ti pare tabi ki o wasi opin. Ohun ti o daraju ti o sele si eda-enia ni **ore-ofe Olorun**. Lotito gbogbo ise Oluwa ni o ti gba **ore-ofe re**, ni ona kan tabi omiran. Wiwa laaye re ore-ofe Olorun ni, awon ti o ti ku paapa ti gba ore-ofe Olorun nigbati nwon mbe ni ipo alaaye.

Olorun bojuwo ile lati orun wa sara awon omo enia, lati wo bi enikan wa ti oye ye, ti o si nwa Olorun. Gbogbo won li o si pada sehin, nwon si di eleeri patapata: ko si eniti nse rere, ko si enikan **Orin Dafidi 53: 2-3, 14: 2-3.** Nitorina, "Koju si mi, ki a si gba nyin la **nipase ore-ofe mi**, gbogbo opin aiye: nitori emi li Olorun, ko si elomiran" **Isaiah 45: 22.**

Ninu awon orisa kosi eyiti o dabi Olorun ti o da orun on aiye. Ko si ise ti a le fi se akawe awon ise Olorun; ni eyiti o tumo si wipe kosi orisa ti o le se awon ise ti Olorun alaaye nse. Iwe mimo wipe "Oluwa, ninu awon orisa ko si okan ti o dabi re, beni ko si ise kan ti o dabi ise re" **Orin Dafidi 86: 8.** O ni orin kan ni ede Yoruba ti o wipe "**O-lore-**

**ofe**, e-leru-niyin, Olorun otito, mo gbe o ga". "Tali o dabi iwo, Oluwa, ninu awon alagbara? Tali o dabi iwo **ologo ni mimo,** eleru ni iyin, ti nse ohun iyanu?" **<u>Eksodu 15: 11.</u>**

Awon enia ni lati mo wipe, gbogbo wa li o ti se, ti a si ti kuna ogo Olorun, sugbon **ore-ofe re** ni o gbe wa ro **<u>Romu 3: 23.</u>** **Ore-ofe Olorun** ni o da wa si titi di oni. Nitorina, o yami-lenu ni isowo ti awon enia fi nyipada kuro lodo Olorun ti o pe nwon sinu **ore-ofe Kristi** si Ihinrere miran tati awon eko ajoji **<u>Galatia 1: 6.</u>** Ni ode oni, awon enia nko Oluwa sile, nwon si nyipada si awon ohun irira ati eeri ati iborisa. Awon enia nko **Ife Isaju** eyiti o mu nwon kuro ninu ajaga ati ide sile, nwon si ntele **ifekufe isaju**, beni won si nko o mora.

Olorun ti mu suru fun awa eda-enia fun akainiye odun; o fi Emi re kilo fun wa, beni o fi jeri gbe wa lati enu awon woli re: sibe awa enia ko fi eti sile: nitorina ni o se fi wa le owo isoro ati okunkun. Sugbon nitori anu re nla Olorun ko run wa patapata, beni ko ko wa sile; nitori on li **Olorun olore-ofe** ati alanu **<u>Nehemiah 9: 30-31.</u>**

Niwon igbati Oluwa je **olore-ofe julo**, Oluwa ndarijin ni, beni o si nfi oju fo awon aisedede wa; ni ona eyiti o mu wa wa laaye loni. Nitorina, enia le wipe **ore-ofe Oluwa wa** po rekoja pelu igbagbo ati ife, ti mbe ninu Kristi Jesu **<u>1 Timoteu 1: 14.</u>**

Ni ikorita yi, a ni lati bere lowo ara wa wipe elo ni a san fun **ore-ofe Olorun** ninu aiye wa? Atipe tani a san owo yi fun? Bi a ko ba san owo kankan fun **ore-ofe Olorun**, a ni lati gba wipe gbogbo ohun-ini wa ninu aiye, pelu ogbon/eko ati ipo wa, ki ise nipa ipa wa tabi agbara wa, bikose **nipa ore-ofe Oluwa** nipase Emi re **<u>Sekariah 4: 6.</u>** Paulu Aposteli jeri si oro otito yi, nigbati o wipe "Sugbon **nipa ore-ofe Olorun**, mo ri bi mo ti ri: ore-ofe re ti a fifun mi ko si je asan; sugbon mo sise lopolopo ju gbogbo won lo: sugbon ki ise emi, bikose **ore-ofe Olorun** ti o wa pelu mi" **<u>1 Korinti 15: 10.</u>** Se afarawe Paulu Aposteli;

mase gbe osuba funrare wipe mimo-se re, tabi ogbon re, tabi agbara re, tabi ipo re,ni o mu o se aseyori lori awon adawole re: sugbon gbe osuba fun **ore-ofe Olorun** ti o mu o se aseyori ati aseyege. Siwaju si, mase gba **ore-ofe Olorun** lasan, bikose ki o lo ni ona ti o dara, ti yio si mu itesiwaju ba ise re.

Ara ninu Oluwa, labe botiwu kori "Olorun yio se ore-ofe fun eniti yio nfe se ore-ofe fun, yio si se anu fun eniti yio se anu fun" **Eksodu 33: 19.** O ku si o lowo lati se awon ohun ti inu Oluwa dun si, ki o ba le da ore-ofe le o lori. Ore-ofe-ki-ore-ofe ti Olorun ba fifun o, ki ise lati bojuto ara re nikan, sugbon nitori anfani awon enia ti o yi o ka ni, ki ise Oluwa ba le tesiwaju ni ile alaaye **Efesu 3: 2.** Ma lo ore-ofe ti Olorun fifun o ni gbogbo igba, lati bojuto awon enia toku.

## Ore-ofe Olorun ni o mu Ihinrere wa

Ni ibere pepe, lehin isubu eda-enia ninu ogba Edeni, awon enia beresini ko Irira, ati eeri ati iborisa mora, titi di igba ti Olorun pe Abrahamu ti o si ba da majemu. Niwon igbati Olorun wa je **Olorun olore-ofe** ti o kun fun anu pupo fun awon ise owo re, pataki-julo awa enia **Orin Dafidi 145: 8.** O ran Omo bibi re kansoso wa si aiye, fun itankale Ihinrere, A kowe re wipe, "Oro na si di ara, on si mba wa gbe; awa si nwo ogo re, ogo bi ti omo bibi kansoso lati odo Baba wa, **o kun fun ore-ofe ati otito" Johannu 1: 14.**

Awa enia a ngba **ore-ofe kun ore-ofe**, ibukun kun ibukun, ojurere kun ojurere, ati ebun kun ebun lati inu ekun-rere ore-ofe Oluwa **Johannu 1: 16.** Fun idi eyi, "Nipase Mose li a ti fi ofin funni, sugbon **ore-ofe ati otito** tipase Jesu Kristi wa" **Johannu 1: 17.** Lati isinyi lo, a ni lati mo wipe ore-ofe wa lati ipase Jesu Kristi Oluwa wa, eniti o mu Ihinrere wa sinu aiye: nitoripe "Oluwa li **Olorun ti o kun fun iyonu ati ore-ofe" Orin Dafidi 86: 15.**

**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

## Ore-ofe Olorun to fun o

Mo fe ki awon enia mo wipe, ore-ofe Oluwa ni o npese fun aini nwon. Niwon igbati Olorun je alanu ati **olore-ofe**, ti o lora ati binu, ti o si po li iyonu ati ife **Orin Dafidi 103: 8.** Oluwa koni gbagbe lati bojuto awon aini re; yio mu o duro, yio si ti o lehin ni jakejado igba aiye re, bi o ba gboran ti o si se otito.

Bibeli fi idi otito yi mule, nipa kiko wipe "Oju gbogbo enia nwo o; iwo si fun won li onje won li akoko re. Iwo si owo re, iwo si te ife gbogbo ohun alaaye lorun. Olododo li Oluwa li ona re gbogbo, o si je **alanu ati olore-ofe** ni ise re gbogbo" **Orin Dafidi 145: 15-17.** Paulu Aposteli na jeri gbe oro yi, nigbati o mbe Oluwa fun iwosan nitori ailera re; Oluwa dahun wipe "**Ore-ofe mi to fun o**, nitoripe a so agbara re di pipe ninu ailera" **2 Korinti 12: 9.** Nitorina, ohunkohun ti o le ma sele ninu aiye re, **ore-ofe Olorun** to lati yanju won.

## Awon igbese lati ri ore-ofe Olorun gba

Opolopo ni awon igbese igbagbo ti awon enia le gbe lati ri ore-ofe Oluwa gba. Ninu won ni awon ti ao menuba yi:

**Mase je eni-buburu:** Mase se aburu ninu gbogbo adawole re, bi o ba fe ri ohun rere gba lati odo Oluwa, nitoripe "Alafia ko si fun awon enia buburu, li Oluwa wi" **Isaiah 48: 22.** Bi o ba nfe lati ri ore-ofe gba lati odo Oluwa mase je eni-buburu. A kowe re wipe, "Bi a ba fi ojurere han enia buburu, Ki yio ko ododo: ni ile idurosinsin li on o huwa aisoto, ki yio si ri olanla Oluwa" **Isaiah 26: 10.** Niwon igbati Olorun mo wipe, bi a ba fi ojurere han enia buburu koni yipada lati se rere. Mase je alaburu-enia ki o le ri ore-ofe gba lati odo Oluwa.

**Je onirele okan:** Ara ninu Oluwa, irele je okan lara awon iwa ti o dara-julo ti enia le ni; nitorina, e re ara nyin sile niwaju awon enia,

paapa-julo niwaju Oluwa, Ki Oluwa ba le gbe yin ga, ki o si fun yin ni **ore-ofe** **<u>Jakobu 4: 10.</u>** Niwon igbati Olorun je olore-ofe julo, o nfun wa ni **ore-ofe** pipo. Idi niyi ti iwe mimo se wipe, "Olorun ko oju ija si awon agberaga, sugbon o fi **ore-ofe** fun awon onirele okan" **<u>Jakobu 4: 6.</u>** Bi o ba fe ki Olorun fun o ni **agbayanu ore-ofe**, re ara re sile niwaju re.

**<u>Rin dede niwaju Oluwa:</u>** Bibeli wipe, "Nitori Oluwa Olorun li orun ati asa: Oluwa yio fun ni li **ore-ofe ati ogo**: ko si ohun rere ti yio fa sehin lowo awon ti nrin dede" **<u>Orin Dafidi 84: 11.</u>** Fun ore-ofe ati ogo ma rin dede.

**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Ketadinlogbon: Osu Keje Ojo Keji, 2017**

**Akori Oro: Ore-ofe Oluwa** –Apa Keji

**Eko kika: Efesu 2: 1-8**

Ao tesiwaju ninu eko wa nigbati ao ma soro nipa bi eda-enia ti ri igbala gba nipase ore-ofe Olorun.

**Igbala nipase ore-ofe**

Ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa, ni o mu igbala aiyeraye wa fun iran eda-enia, nipase irapada kuro ninu ese. Nitorina, ri daju pe o ko si ore-ofe ti Oluwa fifun o lo.

**Iku nipa Adamu, Iye ninu Kristi:** Awon enia ni lati mo wipe iyato-nla ni o wa larin ese Adamu ati ebun-ofe Olorun. Nitori bi nipa ese okunrin kan Adamu, eni pupo ku, melomelo li ore-ofe Olorun ati ebun ninu ore-ofe okunrin kan, Jesu Kristi di pupo fun eni pupo. Eyi tumo si wipe, a kole fi ebun-ofe Kristi se akawe ijakule ti Adamu; nitoripe iku joba nipase ese Adamu, nigbati ore-ofe ati ebun-ofe wa nipase ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa. Esii ebun-ofe Olorun yato si esii ese Adamu ti o mu idalebi wa, nitoripe o mu idalare wa nipase ore-ofe Kristi ati ododo fun awa eda-enia; bi o tile je wipe a ti jebi opolopo ese. Nje bi nipa ese okunrin kan iku joba nipase enikanna; melomelo li awon ti ngba opolopo ore-ofe ati ebun ododo yio joba ninu iye nipase enikan, Jesu Kristi **Romu 5: 15-17.** A ri aridaju lati inu ese yi, wipe, ore-ofe Kristi Jesu ni o se irapada wa kuro ninu awon ese wa.

**Ore-ofe ni a fi gba nyin la:** Ma ranti ni igba-gbogbo wipe ore-ofe Kristi ni o fun o ni igbala, bi o tile je wipe awa eda-enia ti ku nipa ti emi, nitori irekoja ati aisedede wa. Olorun ninu akailopin anu re, mu wa wa laaye ninu idapo ati isokan pelu Kristi. Olorun fun wa ni iye,

nigbati o ji Kristi kuro ninu oku; nipa ore-ofe ni a fi gbawa-la, ti a si gba wa kuro lowo idajo, ki a ba le je alabapin Igbala Kristi. A kowe re wipe "Nigbati awa tile ti ku nitori irekoja wa, o so wa di aaye pelu Kristi: ore-ofe li a ti fi gba nyin la" **Efesu 2: 5.** Ni bayi a le fi igboiya so wipe, ki ise oke-isoro nla ni yio duro ni oju ona aseyori wa ti ki yio di petele, besini ao si yo lori won nitori ore-ofe Olorun. Bibeli wipe "Tani iwo, iwo oke nla? Iwo o di petele niwaju Serubbabeli: on o si fi ariwo mu okuta tente ori re wa, yio ma kigbe wipe, Ore-ofe, ore-ofe si i" S**ekariah 4: 7.**

**Ofin mu ki ese tan-kale:** Idi ti afi fi ofin-mewa fun Mose ni ki awon enia le riran ri bi ese nwon ti po to, ki won si se atunse: kakabe nse ni awon enia tun gberege-di-ge ninu irekoja, sugbon ore-ofe Oluwa di pupo rekoja. Pe gegebi ese ti joba nipa iku, nitoripe iku li ere ese; beni ki ore-ofe si le joba nipa ododo titi iye ainipekun nipase Jesu Kristi Oluwa wa **Romu 5: 20-21.** Bi o ba fe lati jogun iye ainipekun, gbadura fun ore-ofe ti ibori ese lowo Olorun.

**Igbega lati eru ese si omo Olorun:** Bi o ba nse ohun ti inu Oluwa dun si, ti o si je eni-idurosinsin niwaju Olorun; ese ki yio ni agbara lori re mo, nitoripe iwo kosi labe ofin bi eru, sugbon o wa labe ore-ofe. Bi o ba ti se atunse ajosepo ti o wa larin iwo ati Olorun ao gba o la. Ese ki yio ni ipa lori re, beni ki yio je oluwa re, toripe iwo kosi labe ofin, bikose labe ore-ofe, eyiti o se afihan igbega re lati eru-ese si omo-Olorun. Kiyesara, sa fun ese, mase tesiwaju lati ma dese nitoripe o ko si labe ofin **Romu 6: 14-15.** Ya ara re soto, je mimo; nitoriti Emi je mimo, ni oluwa wi: ki o maba pada sinu ajaga **Lefitiku 11: 45, 1 Peteru 1: 16.** Niwon igbati o ti wa lara awon iyanfe ti ore-ofe ni akoko yi, mase wu iwa ti o le muki a gbegile igbega 'lati eru si arole' re **Romu 11: 5.**

**Irapada nipase ore-ofe Kristi:** Jesu Kristi ni ife awa enia, debipe o ku ki awa le di alaaye: A ka mo awon arufin, ki awa le di eni-mimo.

Bibeli wipe "Nitori enyin mo ore-ofe Oluwa wa Jesu Kristi, pe bi on ti je oloro ri, sugbon nitori nyin o di talaka, ki a le so nyin di oloro nipa aini re" **2 Korinti 8: 9.** Ona kansoso ti a fi le fi emi-imore han fun ore-ofe ailegbe re, ni ki a yera fun ese, niwon igbati a ti rawapada. A kowe re wipe "Ninu eniti awa ni irapada wa nipa eje re, idarijin ese wa, gege bi oro ati ore-ofe re" **Efesu 1: 7.** Nitorina, a ni lati jewo wipe irapada awon ese wa, nipase Jesu Kristi nikan ni: atipe ore-ofe re ni o gbawa-la. Awon woli igbaani so asotele ti ore-ofe ti mbo fun wa, nwon se iwadi-kunakuna, nwon si wa ijinle nipa ti Igbala ti a nsoro re yi; sugbon o seni lanu wipe Igbala ko farahan ni akoko tabi igba tiwon **1 Peteru 1: 10.** Iwo ti o je alabapin ninu Igbala yi, di Igbala-ofe yi mu sinsin, ki o ma ba lo aiyeraye re ni orun-apadi.

**Idalare nipase ore-ofe:** Awa enia ni lati fi tokantokan wa ore-ofe Olorun, nitoripe ninu re ni a ndawa-lare lofe: ni eyiti o je wipe o mu wa bo lowo ebi-ese, ti o si se wa ni eni-itewogba niwaju Olorun nipase ore-ofe ti mbe ninu irapada ti o wa ninu Kristi Jesu. Ore-ofe Olorun ni o so wa di olododo niwaju re, ti o si fun wa ni iye ainipekun: awa eniti a ndalare lofe nipa ore-ofe re, nipa idande ti o wa ninu Jesu Kristi **Romu 3: 24.** Nitorina, mase gbagbe wipe ore-ofe Olorun ni o dawa-lare lofe, nipase Kristi Jesu ti o tuwa sile, ti o si gba wa kuro lowo idajo awon ese wa. Ara ninu Oluwa, e mase si ore-ofe yi lo: ore-ofe ti nda-ni lare, ti o so wa di arole si Olorun, ti o si fun wa ni ifokan-bale wipe ao jogun iye ainipekun **Titu 3: 7.** E mase bi Kristi ninu, eniti o se awon ohun-rere fun wa lopololpo, ti o se wa ni eni-itewogba niwaju Olorun Baba re, ti o si fun wa ni ireti iye ainipekun.

**Itunu ati ireti:** Jesu Kristi Oluwa wa tikarare, ati Olorun Baba wa, eniti o fe wa, ti o si ti fi itunu ainipekun ati ireti rere nipa ore-ofe fun wa **2 Tessalonika 2: 16.** Niwon igbati Jesu Kristi ati Olorun Baba wa yio fun wa ni itunu ati ireti rere fun igbala nipase ore-ofe; e jeki a ni igbagbo wipe ona kansoso ti a fi le gbawa-la ni nipase ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa. Igbala otito kansoso ti ki ise aiyederu ni nipase ore-

ofe Jesu Kristi **Ise awon aposteli 15: 11.** Mase gbagbe wipe igbala Olorun wa nipase ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa.

**Iyorisi ore-ofe**

Iyorisi ore-ofe Olorun ni irapada awa eda-enia, gegebi ese Bibeli ti o wipe "Nitori Olorun fe araiye tobe ge, ti o fi Omo bibi re kansoso funni, ki enikeni ti o ba gba a gbo ma ba segbe, sugbon ki o le ni iye ainipekun" **Johannu 3: 16.**

**Wiwa Messiah sinu aiye:** Ore-ofe Olorun ni o mu Messiah wa sinu aiye. O wa sinu aiye lati fun wa ni idande kuro ninu awon ese wa. Angeli kan polongo fun awon oluso-aguntan wipe "Nitori a bi Olugbala fun nyin loni ni ilu Dafidi, ti ise Kristi Oluwa" **Luku 2: 11.** Jesu Kristi Olugbala mu igbala-aiyeraye wa fun awa eda-enia. Iwe Titu jeri gbe oro yi wipe "Nitori ore-ofe Olorun ti nmu igbala fun gbogbo enia wa ti farahan". Jesu Kristi ni ore-ofe ti o mu igbala wa fun gbogbo eda-enia **Titu 2: 11.**

**Atunbi, iwa-bi-Olorun ati iwarere:** Igbsi-aiye awon kristiani ti ise ife Oluwa ni ao so si otun, debipoe awon enia yio ri ayipada rere ninu aiye nwon. Gegebi a ti ko ninu Bibeli wipe, "Nitorina bi enikeni ba wa ninu Kristi, o di eda titun: ohun atijo ti koja lo; kiyesi i nwon si di titun" **2 Korinti 5: 17.** Awon enia atunbi wonyi gbodo ma huwa-rere ati iwa-bi-Olorun ninu gbogbo adawole nwon. Awon wonyi gbodo gbekele ore-ofe Olorun ju ogbon-ori enia lo ninu gbogbo igboke-gbodo ati ajose nwon ninu aiye. Iwe mimo wipe, "Nitori eyi ni isogo wa, eri-okan wa, pe, ni iwa-mimo ati ododo Olorun, ki ise nipa ogbon ara, bikose nipa ore-ofe Olorun, li awa nhuwa li aiye, ati si nyin li opolopo" **2 Korinti 1: 12.** Mase gbagbe ore-ofe Olorun ti o fun o li agbara lati huwa-mimo ati iwa otito.

**Awon ebun Emi Mimo:** Ore-ofe Olorun li o fi awon ebun Emi-mimo

kun aiye re, gegebi asotele ti a ko sinu Iwe Joeli "Yio si se, nikehin emi o tu emi mi jade si ara enia gbogbo; ati awon omo nyin okunrin, ati awon omo nyin obinrin yio ma sotele, awon arugbo nyin yio ma la ala, awon odomokunrin nyin yio ma riran: ati pelu si ara awon omo-odo okunrin, ati si ara awon omo-odo obinrin, li emi o tu emi mi jade li ojo wonni" **Joeli 2: 28-29.** Ore-ofe Olorun ti mu asotele yi se ninu aiye loni: idi niyi ti ebun Emi-mimo se tankale ti o si po pupo larin awon kristiani; nitoripe igba-ikehin ni a wa. Nitorina, ebun-kebun ti Olorun ba fifun o, lo daradara fun igbedide ati anfani awon enia ti o yi o ka, gegebi olotito omo-odo ti ore-ofe Olorun. Gegebi a ti kowe re wipe, "Bi olukuluku ti ri ebun gba, beni ki e se ipinfunni re larin ara nyin, bi iriju rere ti oniruru ore-ofe Olorun" **1 Peteru 4: 10.** Mase je onimo-tara-eni-nikan; lo awon ebun re lati fi gbe awon enia ro ati fun anfani nwon.

## Awon adura fun ore-ofe

Ore-ofe Olorun se Pataki, o se koko, o si je kose-mani fun awa enia: idi niyi ti a fi ko opolopo adura fun ore-ofe Olorun sinu Bibeli. Meji ninu awon adura yi, ni a menuba ninu opo ese Bibeli, awon na ni awon wonyi:

- Ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wa pelu gbogbo nyin. Amin. **Romu 16: 24, 1 Korinti 16: 23, Filippi 4: 23, 1 Tessalonika 5: 28, 2 Tessalonika 3: 18, Ifihan 22: 21.**
- Ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wa pelu emi nyin. Amin. **Galatia 6: 18, Filemoni 1: 25.**

Nitorina, e mase fi awon adura mejeji yi sere, ki ore-ofe Jesu Kristi le wa pelu nyin ati pelu emi nyin titi lailai.

**Ore-ofe, anu ati alafia:** Bere ki Oluwa se oju re ki o mole si o lara, ki o fi ore-ofe yi o ka, ki o se ona re ni ire, ki o si mu gbogbo erongba-okan re se nipase anu re **Numeri 6: 25,** Ki ore-ofe, anu ati alafia re ba le ma ba o gbe titi lai **1 Timoteu 1: 2.**

**Ki ore-ofe wa pelu awon eni-mimo:** Gbadura si Olorun Olodumare ki o fun awon eni-mimo ni ore-ofe. Bere ki ore-ofe wa pelu gbogbo awon ti o fe Oluwa wa Jesu Kristi li aisetan. So fun Olorun ki o ma to isise nwon, ki o si pa nwon mo bi eyin oju, ni gbogbo ojo aiye won. **Efesu 6: 24.**

**Igboiya ati ore-ofe ti nran-ni-lowo ni igba isoro:** Sunmo ite ore-ofe pelu idaniloju lati le gba anu ati ore-ofe iranlowo. Awon kristiani ni lati fi igboiya wa si ibi ite ore-ofe, ki nwon le ri anu gba, ki nwon si ri ore-ofe lati ma ran-ni-lowo ni akoko ti o wo **Heberu 4: 16.**

**Ore-ofe lati te ori Satani ba:** Gbadura si Olorun ki o fun o ni ore-ofe lati jeri arekereke Satani, ki o si dojuti lori oro aiye re. Bere ki Olorun fun o ni ore-ofe ti yio so Satani ati awon omo-lehin re di itemole labe ese re. So fun Olorun alafia, wipe akoko tito lati te Satani mole li atelese re; ki ore-ofe Jesu Kristi Oluwa wa le farahan ni kikun ninu aiye re **Romu 16: 20.**